**Lakaye Ọrọ**

OLUKULUKU ohun ni akoko wa fun, ati igba fun isẹ gbogbo labẹ ọrun. Igba bibini ati igba iku. Iran kan nlo, iran kan mbọ ṣugbọn aiye duro titi lai.


# Irohin Yoruba

No. 806 NOVEMBER 16 — NOVEMBER 22, 1960 KOBO MEJI (2D)






Jẹ egbogi ti o daraju fun ọmọde

O wa fun tita kakiri Ile-egbogi


# ẸGBẸ ỌMỌ ODUDUWA Ṣ'AJỌDUN KẸTALA

## *Azikiwe di Gomina-Agba*



DOKITA AZIKIWE

* * *

Loni ni nwọn yio fi Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe je Gomina-Agba Apapọ Ijọba Naijiria.

## Akintọla fun Gomina Agba ni ẹbun nla

IBADAN.

NINU irin-ajo idagbere ti Ọlọla James Robertson, Gomina-Agba Apapọ Ijọba Naijiria ṣe ni Ibadan laipẹ yi ni Ọlọla Ọba Alaiyeluwa Adesọji Aderẹmi Kini Ọni Ifẹ ti i ṣe Gomina Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun gbe pe ase apejẹ nla fun on ati aya rẹ. Lẹhin ipari ase yi ni Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ati aya rẹ, Oloye Faderera Akintọla gbe tun ṣe eyẹ nla kan fun Gomina-Agba na ati iyawo rẹ, nwọn si fun wọn ni ẹbun nla ti o joju.

Inu Gomina-Agba na ati aya rẹ dun pupọ.



IBADAN

GẸGẸBI eto ti nwọn ti ṣe tẹlẹ pe ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ni nwọn yio ṣe ipade ajọdun kẹtala Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa ni Ibadan, bẹẹ na ni nwọn ṣe e.

Nigbati ọjọ na ti ku ọla ni gbogbo awọn Oba, awọn Ijoye ati awọn enia pataki-pataki ninu Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa ti o wa kakiri ilu Naijiria ti pesẹ si Ibadan, nwọn si ṣe aisun ajọyọ moju ọjọ ipade nla na.

Nigbati o di owurọ kutu hai ọjọ na gbogbo wọn ti miira lati lọ fi isin idupẹ bẹrẹ ipade ajọdun na ni Ṣọọṣi St. Peter's, Arẹmọ, Ibadan, ẹniti o si ṣe alakoso isin na ni Alufa-Agba Archdeacon Dọkita Lucas, Alabojuto Ṣọọṣi St. Paul's Breadfruit l'Eko.

Lẹhin ti nwọn pari isin idupẹ tan, nwọn bẹrẹ ipade na ni Gbọngan Apejọ Oke Mapo. Ẹniti o ṣe Alaga ni Ọba Alaiyeluwa I. B. Akinyẹle, Olubadan Ibadan, o si ka ọrọ ayẹsi ikini-kuabọ fun gbogbo ipade ẹgbẹ na.

Lẹhin iyẹn, ni nwọn wa ṣe eyẹ nla kan pataki fun Baba-isalẹ wọn, Ọlọla Ọba Alaiyeluwa Adesọji Aderẹmi Kini, Ọni Ifẹ ti i ṣe Gomina Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun. Nibi aṣeyẹ na ni nwọn fun un ni iwe-ayẹsi ikini-ku-orire ti aye Gomina ti o bọ si, nwọn si fun un ni ẹbun ọpa wura ati aga oniyebiye. O si dupẹ fun wọn pupọ fun ẹbun ti nwọn fun un yi, o si gbadura fun ilọsiwaju Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa.

Aworan oke akọko yi ni ti igbati Ọlọla Ọba Alaiyeluwa, Ọni Ifẹ nfesi si ọrọ ayẹsi ti awọn Ọmọ Oduduwa fi fun un ni ẹbun. Aworan keji ni ti igbati Ọlọla Ọni pelu Oloye Dọkita Akinọla Maja Baba-ẹgbẹ awọn Ọmọ Oduduwa nsọrọ.

# Balewa ni Ijọba kan ko le tu Ijọba miran ka

## O dupẹ lọwọ awọn ara Ipinlẹ Iwọ-Orun

OLỌLA Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Ijọba Apapọ Naijiria pari abẹwo Ipinlẹ Iwọ-Orun ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi. O bẹrẹ abẹwo Ipinlẹ na ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi, gbogbo ibikibi ti o si de ni o gba iyi ati ẹyẹ awọn ara ilu. O lọ kakiri awọn ilu die ti o le de ni Ipinlẹ na.

Ki o to fi Ibadan silẹ wa si Eko ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi, Ọlọla Abubakar dupẹ lọwọ Ijọba ati awọn ara ilu Ipinlẹ Iwọ-Orun fun ẹyẹ nla-nla ti nwọn ṣe fun on, o ni ori on si wu, on si kan saara fun wọn fun nkan ribiribi ti nwọn ṣe fun anfani ati ilọsiwaju Ipinlẹ na.

Ṣaaju ki o to so ọrọ yi, Oloye Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, sọ fun Ọlọla Abubakar pe on na yio ti mo daju nigbati o bẹ awọn wo yi pe, Ipinlẹ Iwọ-Orun ko ni kolokolo kankan si Ijọba Apapọ Naijiria tabi Ijọba Ipinlẹ miran ni Naijiria. O ni gbogbo nkan ti Ọlọla Abubakar si ti ri ni ibikibi ti o ti de ni Ipinlẹ Iwọ-Orun, ati ọrọ ti o ti gbọ lẹnu awọn ti nwọn ti ṣe ariya fun un yio ti fi han an pe Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ngbiyanju lati ma a ṣe nkan anfani fun ilu.

Ẹyẹ abẹwo na pari ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi nigbati Ọlọla Abubakar de ilu Ishagamu. Oloye Akintọla si sin in de ibẹ. Gbara bi nwọn ti de Ishagamu ni Alaiyeluwa Ọba Awolesi, Akarigbo Ijẹbu Rẹmọ ti gba a ni alejo. Gbogbo awọn ọmọ ile-iwe Rẹmọ bẹrẹsi ki i ku-abọ pẹlu asia Apapọ Ijọba Naijiria lọwọ. Oloye Akintọla si fun un ni ẹbun awọn foto oriṣiriṣi ẹyẹ ti o gba ni gbogbo ibi ti o bewo ni Ipinle Iwọ-Orun.

Nigbati Ọlọla Abubakar fi Eko silẹ, Ifọ ni o kọkọ duro, awọn ara Ifọ—Ibo, Hausa ati Yoruba—si ṣe ẹyẹ fun un bi o ti lo ati bi o ti yẹ.

Abẹokuta ni Alakoso Ijọba Apapọ Naijiria na tun duro. Oloye S. L. Akintọla Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ati awọn Minista rẹ meji si lọ pade rẹ. Awọn ọmọ ile-iwe ilu Ẹgba to ni ọna titi Aro de Afin Ake, nwọn si nki i "kabọ" bi moto ayọkẹlẹ ti o wọ ti nlọ loju titi. Ọba Alaiyeluwa Alake Abẹokuta, Ọlọla Ladapọ Ademọla Keji fi iwe ikini-kuabọ yẹ ẹ si ni gbongan apejọ (Centenary Hall) Ake.

Ẹyẹ ọjọ na pọ to bẹ ẹ gẹẹ ti Ọlọla Abubakar paapa fi sọ fun awọn oniwe irohin pe on ko ri iru ẹyẹ bayi ri. Lẹhin eyi ni Ọlọla Abubakar bẹ Ewekoro wo, o si ri i bi nwọn ti ṣe nṣe iṣẹ simẹnti pipo, ki o to rekọja lọ si Ibadan.

Ẹyẹ ti Ọlọla Abubakar gba ni Ibadan buaiya, o lé gongo. Irohin ko to afọjuba ni. Awọn ọmọ ile-iwe yẹ ẹ si, awọn ara ilu lọkunrin ati l'obirin fi tayọ-tayọ ki i k'abọ, Gomina Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, Ọlọla Adesoji Aderẹmi Oni Ifẹ si ki i kuabọ pẹlu. Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun gba a lalejo lẹkun.

(Wo oju ewe kejila)

# Awolọwọ ni on yio ran awọn oṣiṣẹ lọwọ

KADUNA.

NIGBATI Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Apapọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria nba awọn enia sọrọ lori "Aye Awọn Oṣiṣẹ ninu ilu Naijiria ti o di Ominira" ni Gbọngan Iworan Sinima "Rader Cinema Hall" Kaduna, o fi ọwọ sọiya gbangba lati fi ẹsẹ ẹgbẹ oṣiṣẹ ti o lagbara daradara mulẹ ni ilu Naijiria, o si ṣe alaye bi on ti ṣe ri awọn aṣiwaju awọn ẹgbẹ oṣiṣẹ ti o gbogunti ara wọn, ati bi o ti ṣe sọ fun wọn wipe ki nwọn pari ija larin ara wọn, ki nwọn si fi owo sowopọ ki nwọn ba le gba ipin orire tiwọn ti a npe ni owo-ọmọ-ibile.

Oloye na si ṣe alaye pe, on ko pokiki riri ti on ri awọn aṣiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ na fun gbogbo enia gbọ, ki nwọn ma ba a ro wipe on fi nṣe iṣẹ iṣelu ni, o si ṣe alaye iru ọrọ ti on ba wọn sọ pe ki nwọn lọ jawọ kuro lara awọn ẹgbẹ oṣiṣẹ ilẹ ajeji, "Ki nwọn da ẹgbẹ oṣiṣẹ ti nwọn silẹ, ki nwọn si da owo ti nwọn yio ma a na laiko gbẹkẹle owo ti ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ ilẹ ajeji". Nitoripe, bi nwọn ba binu da iṣẹ silẹ ti nwọn ko si lowo lọwọ, iya yio jẹ wọn, ṣugbọn ki awọn aṣiwaju wọn ma a ṣe otito.

Oloye Awolọwọ ni owo ti nwọn ngba ko to fun wọn, o ni iwọn-iba owo-ori ni Ijọba Ẹgbẹ Afẹnifẹre ngba, ṣugbọn owo ti o to lati fi jẹun ati lati lọ ni awọn nsan fun awọn oṣiṣẹ, o ni onjẹ die ni awọn akọwe njẹ, ṣugbọn awọn oniṣe agbara nfẹ onjẹ pupọ, sibẹsibẹ onjẹ awọn mejeji nilati dara bakanna.

O ni owo ti nwọn san fun awọn oṣiṣẹ Ipinlẹ Ila-Orun ati Ariwa ko pọ to ti Ipinlẹ Iwọ-Orun rara atipe lẹhin sisan owo iṣẹ yi, Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun tun npese ile daradara fun awọn oṣiṣẹ pẹlu. O ni o yẹ ki ile-iwe ọfẹ wa fun awọn ọmọde yika gbogbo Ipinlẹ, o si yẹ ki awọn oṣiṣẹ tubọ jaramọṣẹ daradara nitori bi iṣẹ ba pọ, owo rẹ yio pọ. O si sọ wipe on ti fi imọran ẹkunwo na si iwaju Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria pẹlu, o ni bi Ijọba ko ba tete sọ si ọrọ na larin oṣu yi, on yio pokiki ọrọ na yika gbogbo ilu. Ọgbẹni S. G. Ikoku, Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun ni o ṣe Alaga ipade na.

## CLASSIFIED ADVERTISEMENTS

OGUN. Iṣoye 5s. post owo si MANAGER Box 73. Ilesha.

**AKIYESI**

6th, 7th, 8th & 9th Books of Moses lede Yoruba £1. pere. A le ri ra ni 15, Araoti Street Yaba Nigeria

**MOJUBA AIYE**

ANTA ọja oriṣiriṣi to jẹmọ Ogboni ati ohun anfani miran. Fi stamp onitoro (3d. stamp) ranṣẹ fun Iwe Aiye Akamara. Kọwe si—APENA, 75, Haastrup Street, Suru-Lere, Yaba Nigeria.

**ỌJA ALAFIA**

IWE Psalmu pẹlu turari 10s. 6d., Iwe Ifa Agbonniregun 25s., Ajo ilu Egypt tun ọja tita £2. Ọṣe Adure ilu India £1. Iwe Egbogi Ajẹbidan 30s., Ajo Iyonu awọn Agba £1. OLOTU Box 349 Mushin .Lagos.

OLOKUN—Inu wa dun pupọ lati sọ fun gbogbo ẹnyin onibara wa pe ati bẹrẹsi ta apa keji iwe atigbadegba. E le ri i ra ni Yoruba Historical Research Scheme P. O. Box 730, Ibadan. Tabi ni awọn ile itawe gbogbo. Ṣile kan abọ pere ni.






# Itan iṣẹdalẹ ilu Ijẹbu-Ijẹsha

**Nibiti a ba itan na de ni ọsẹ ti o kọja ni ipari ọsẹ itan na ni, "Ọba Ijẹbu Jesha ni awọn oloye tirẹ ti o nfi jẹ oye ni Afin rẹ. Awọn ijoye rẹ ti o nfi jẹ oye ninu Afin rẹ to adọjọ (150). Ninu awọn oloye wọnyi, awọn oloye obirin wa ninu wọn pẹlu."**

AWỌN IJOYE MẸJỌ

Awọn Oloye pe si orisi mẹjọ. Awọn ni wọnyi: (a) Iwarẹfa mẹfa. (b) Ẹgbẹ Arẹ. (d) Ẹgbẹ Iwọle (e) Ẹgbẹ Lẹgbẹwa. (ẹ) Ẹgbẹ Esemure (awọn obirin) (f) Olori ọmọ mẹrin. (g) Awọn Aworo mẹfa (Head of idol worshippers) ati awọn ijoye miran ni agbegbe. (gb) Idamẹrin awọn Ijoye nṣe ipade awọn Oloye ni Afin ni ọjọ marun-marun. Ṣugbọn nisisiyi a ti sọ ọ di ọjọ mẹjọ-mẹjọ ọjọ Aje (Monday).

(h) Ọba Ijẹbu-Jẹsha ni awọn Ẹgbẹ Onisegun, Olori awo Isegun ni Olori wọn (Medical Officer and Nursing Staffs) (i) Ọba Ijẹbu-Jẹsha ni awọn Ẹgbẹ Awo ti a npe ni Babalawo (seers) eyiti o jẹwipe Oluawo ni Olori wọn. (j) Ọba Ijẹbu-Jẹsha ni awọn ọlọdẹ (hunters) Lumogun ni olori wọn, Tọbalasẹ si ni Atẹle rẹ.

(K) Ọba Ijẹbu-Jẹsha ni awọn Gbẹnagbẹna, eyiti Oshunmu jẹ olori wọn. Awọn gbẹnagbẹna yi ni nwọn ngbẹ aworan (statue) awọn ara igba atijọ, awọn ni nwọn ngbẹ awo- onjẹ (wooden-plate) fun ọba ni ọdọọdun, ati odo ti a fi ngun iyan, ipọn ti a fi nro ọbẹ, ọkọ oju-odo ati awọn nkan afigise bẹẹbẹ pẹlu.

ibilẹ bi a ti ṣe ntọrọ ọmọ ati bi a ti ṣe nfi ọmọ funni lati fi ṣe aya (r) Ijẹbu-Jẹsha ni aṣa-ibilẹ bi a ti ṣe nfi enia joye. (s) Inu mi yio dun bi Ijọba ba le ran enia wa bẹ ilu wa na wo, nwọn yio si ba gbogbo awọn nkan atijọ ti o di itan loni na nibẹ, ṣugbọn a ko nṣe idajọ fun apania mọ nibẹ lati igbati Ijọba Gẹẹsi ti de si Naijiria

IPADE AṢOJU ỌBA

Ni ọdun 1886 ni Ijọba Gẹẹsi pa Ijẹbu-Jẹsha pọ mọ Ilesha fun Ipade Aṣoju Ọba ilu Oyinbo, nwọn tun pa Ekiti Ijesha pọ si oju kanna fun ipade ṣugbọn nigbati ajumọsepọ Ijẹsha ati awọn Ekiti ko dọgba nitori iwa itẹniloriba ti Ilẹsha nhu si wọn, ni nwọn ba pada si aye wọn.

(r) Oloye Adoko jẹ ọmọ

ohun ti o ba tọ fun Iṣakọlẹ lati ọdọ awọn ti o ba wa ni ori ilẹ Ọba Ijẹbu-Jẹsha wa fun Ishakọlẹ ọdọọdun Odudua Baba nla wa ni o nje Ogun.

OGBONI IJẸBU

(t) Ki Ijọba Gẹẹsi to fi Ipade Apapọ si Ilesha, "Ọba Ijẹbu-Jẹsha" ni Ọba Ijẹbu njẹ. Ṣugbọn nigbati o di ọran iwe akọsilẹ ni ọdun 1902 ni awọn ara Ilesha sọ pe ki nwọn kọ orukọ na ni Ogboni Ijebu.

Ọwaoye ni Lọja Imẹsi-Ile njẹ tẹlẹ. Lori akọsilẹ yi ni awọn ara Ilesha fi ni ki nwọn ma a pe e ni Lọja-Imẹsi; Ọwa miran ni Lọja-Ẹsaoke njẹ tẹlẹ, lori ọran akọsilẹ yi ni awọn Ilesha ni ki nwọn ma a pe e ni Lọja-Ẹsaoke;

(Wo oju ewe kẹsan)

## Lati ọwọ Alaiyeluwa Arojojoye Keji, Ọba Ijẹbu-Ijẹsha

ALAGBẸDẸ ỌBA

(l) Ọba Ijẹbu-Jẹsha ni awọn alagbẹdẹ, Sajowa ni orukọ olori wọn njẹ. Awọn alagbẹdẹ yi ni o nrọ iso ti a npe ni Eṣerin, Ada, ọkọ, oko-ibọn, awọn ohun-ija onirin ati bẹẹ bẹẹ lọ.

(m) Ọba Ijẹbu-Jẹsha ni awọn Iranṣẹ (messengers) ti a npe oruko wọn ni EMESE, Olori wọn ni Oloye Ọbalaye (n) Ọba Ijẹbu-Jẹsha ni awọn ọmọ Ẹgbẹ-ogun tabi jagun-jagun soldiers). (o) Ọba Ijẹbu-Jẹsha ni ẹniti o nsin ade fun un, orukọ rẹ nje Asẹde. (ọ) Ọba Ijẹbu-Jẹsha nfun awọn enia rẹ ni ilẹ lati fi kọ ile ati lati fi da oko gẹgẹbi aṣa iṣẹdalẹ.

(p) Ijẹbu-Jẹsha ni aṣa-

ọmọbirin Ọba Ijẹbu-Jẹsha Idi eyi ni o mu ki Ọba Ijẹbu-Jẹsha fi Oloye Adoko si arin meji oko rẹ pe ki o ma a mu oju to ire-oko rẹ fun un. Adoko na si wa ni oko (Idoko) na titi di oni yi.

(s) Ọdọọdun ni Ọba Ijẹbu-Jẹsha nṣe Ọdun-Ogun (Oro-ọdun-ogun, oṣu kini ọdun (January) ni akoko rẹ mbọ si. Oro Ọdun Ogun yi ni a gbọdọ tete ṣe ki awọn ara ilu to ma a lọ ṣan oko ajọdun. Gẹgẹ bi iṣe awọn agbẹ, ki aṣiṣe tabi ifarapa ma ba a si fun wọn ni oko gbogbo ilu ati ereko Ọba Ijẹbu-Jẹsha ni nwọn ma a nda isu, oguro, epo, ẹran igbẹ obi-abata ati gbogbo


## WO IKỌ FEE SAN
### Sun un bi ọmọde

A ni igbekele si I, lẹbẹko, a o Ma owo rẹ pada.

FW 22

Le awon aran jade



Egbogi aran

# DEWITT'S Worm Syrup

nko awon ARAN-EEPA ati ARAN-MUJE-MUJE jade. Awon aran ti o wa ninu re ko dara fun o. Nwon ndagba nitoripe nwon nji ayiti o darajulo ninu onje ti o ba je. Nitorina ni aisan fi nse o, o ko si ngbadun ara re ki o si lagbara dada.

Enikeni le fi egbogi alagbara titun ti a npe ni De Witt's Worm Syrup le awon aran inu re jade. O nda awon aran ni ijakadi, nipa bayi, nwon nilati jade kuro ninu ara re. Nigbana ara re yio le, wa a si tete ni alafia pelu; Iyanu ni o je fun awon omode pelu, nwon feran adun re legu. Pelu igo kookan De Witt's Worm Syrup ni wa a ni iwe apejuwe kan. Yio so ohun ti wa se gan an fun o.



LEHIN NA —
Ara re le, okan re si bale. A dupe lowo De Witt's Worm Syrup




# Ọti Atẹjẹṣe Yi L'Oso Dẹjọ Di Elere Iyanu

*Ẹ Ka nhan ti ọti Atẹjẹṣe*

PHOSFERINE TONIC WINE *se fun Dẹjọ Fayẹmi ọmọ Nigeria ti o di Olokiki ninu awọn agbabolu*





**Lọ Si Sọbu Ibiti O Ti Nra Ọja Kiakia ki O Si Ra Ọti Waini Atẹjẹṣẹ, PHOSFERINE TONIC WINE Fun Ara Rẹ**

*Kọwe si Phosferine Tonic Wine, P.O. Box 431, Lagos fun iwe kekere ni ti O sọ bi O ti le ni ilera*

# Awọn ọmọ ilu Ọyan ṣe ipade nla lori ọrọ oye Ọlọyan Ọyan

AKA.

GBOGBO awọn ọmọ Ọyan ti nwọn wa ni Ile-Ifẹ ati agbegbe rẹ ṣe ipade nla kan ni ilu Oru ni ọjọ Aiku ti iṣe ogbọnjọ oṣu kẹwa ọdun yi lori awọn ohun pataki ti nwọn nfẹ fun ilu wọn ati lori ọrọ oye ti Ọlọyan.

Nwọn bẹrẹ ipade na pẹlu adura lẹhin na ni nwọn tẹnu bọ ọrọ nipa ilu wọn ati awọn nkan anfani ti nwọn ri i wipe ṣiṣe wọn le mu idagbasoke wa fun ilu wọn.

Ọrọ oye ti Ọlọyan ni o dun wọn l'ẹmi pupọ ju. Nwọn ni bi o ti jẹ wipe ọran ilu Ọyan ndun wọn pupọ ọrọ ti Ọlọyan dun wọn julọ, nitoripe "gbọn-mi si omi-koto" ti o wa nidi ọrọ na ko mu ilu ṣọkan, ko si mu ilọsiwaju wa.

Nwọn ni 'gbati awọn ijọba ti ṣe ipinnu lati ṣe iwadi nipa ọrọ oye na, inu gbogbo awọn ara ilu dun, ṣugbọn lati igbati Ijọba si ti ṣe iwadi lati ibẹrẹ oṣu kini ọdun yi ni awọn ti nreti esi iwadi na. Nwọn ni esi na koi ti i de titi ọjọ na, o si jẹ ohun ẹdun ọkan olukuluku pe ọdun na ni o npari lọ yi, awọn ko si gbọ nkankan lati ọdọ Ijọba. Nwọn ni alaimu esi iwadi na wa ko jẹ ki ara ilu o ya, ko si si alafia ni ilu.

(Wo oju ewe kẹsan)


IRORA ORIKE-RIKE ARA DURO nipa pe ki o tete m'ojuto awọn Eree inu ati APO-ITO RẸ





Ki o si bọ lọwọ awọn irora ti o nko ẹ sinu arun LAKUREGBE, ARA-RIRO, ẸHIN-DIDUN ati ati Awọn IYỌNU APO-ITỌ

DeWitt's
Kidney & Bladder Pills



Otutu fẹrẹ ti fun un ni "K O.!"



1. Nigbati o ku ọjọ meji lati ja ija nla na—Battling Sam bẹrẹsi wukọ o si nsin.

2. Alabojuto rẹ ni: "Ọgbẹni —a ni lati le otutu yen lọ ni" Sugbọn ìọna wo! Lẹsẹkẹsẹ ni o ranti—Mentholatum



3. Lẹhinti o fi Mentholatum atura ati adẹra pa ara l'akọ-kọ, Sam bẹrẹsi gbadun. Nigbati o ku wakati diẹ ki o de agbo ni segun ija rẹ ti naro.

4. Ija nla na de, Battling Sam bẹ s'agbo bi amọtẹkun lati gbe onija rẹ sanlẹ lori ija karun. Gbogbo enia ho gee pe "Sam ọọku-tọọ" Sam ni "opẹlọpẹ Mentholatum" "Dajudaju o gbọn otutu mi nu.

Fi Mentholatum bọ inu rẹ—ki o si ma a mi pẹlu iroun. Fi diẹ pa aiya rẹ—ki o si fọwọ ra a wonu! Ikọ rẹ yio lọ laipẹ. Mentholatum atura ati adẹra nsiṣe bi idan ni nigbagbogbo! Mentholatum dara fun jẹdi-jẹdi, pẹlu —a tete mu itura wa! Ri i daju pe ejulowo Men-tho-lay-tum ti o wa ninu awọn ṣangolo ati awọn idẹ gẹgẹbi awọn apẹrẹ wọn yi ti o bere fun. Maṣe ra awọn adamodi!



Awọn nkan ti nwọn nṣe ni
MENTHOLATUM CO. LTD
(Est. 1889), Slough, England

MENTHOLATUM
IPARA TI O DARAJU



Asikò Ovaltine!

Pẹlu ilera ọkan ati ilera ara, ọmọde ndagba di ọkunrin, awọn obi ti o gbọn a ma a fun awọn ọmọ wọn ni Ovaltine mu. O nfi okun ilera rẹ pataki bọ ọpọlọ Ori, awọn iṣan ati ara a si ma a fun agbara ati okun-inu ni agbara kikun. Ebun ẹda atẹjẹṣe ti o darajulọ pẹlu ohun ti o nfun ara ni okun mu ki Ovaltine jẹ ohun mimu ti o dara fun ọdọ ati agba bakanna!



OVALTINE

O nfun awọn ọmọde ni inudidun pẹlu ilera.



# Apapọ awọn ẹlẹsin Iṣẹṣe ṣe isi ominira Naijiria

Ni deede agogo mẹwa abọ owurọ ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu kẹwa ọdun yi ni apapọ gbogbo awọn Ẹlẹsin-Iṣẹṣe Ilẹ Enia-dudu (The Ancient Religious Societies of African Descendants Association) l'Eko ati yika gbogbo agbegbe rẹ ṣe Isin Idupẹ nla kan fun ajọyọ Ominira Apapọ Ijọba Naijiria ti a ti ṣe koja ni ọjọ kini oṣu ti o koja ninu Gbọngan Ile Isin wọn ni Isalẹgangan l'Eko. Bi nwọn si ti pari Isin Idupẹ na ni gbogbo wọn ba tun tatare kọja si ilẹ Baba Ẹgbẹ wọn, Oloye Fagbemi Ajanaku, Araba-Eko lati fi abọ fun un.

Oloye Adisa Shonibarẹ, Agbongbon tọkasi idi apejọ nọ wọn lati dupẹ lọwọ Ọlọrun fun ominira ti Apapọ Ijọba Naijiria gba, nwọn si ṣe iwure kini. Oloye Shonibarẹ sọ pe idi ti awọn fi pejọ ni 'lati fi ọpẹ fun Ọlọrun Olodumare Ẹlẹda ohun gbogbo, ni ede ati aṣa ilẹ enia-dudu fun oore nlanla ti O ṣe fun wa ti O jẹki ilẹ wa Naijiria yi le gba Ominira."

"Lati wure, ki ominira na le tu lọmọde tagba ilẹ Naijiria ati awọn iran ti o mbọ lẹhin lara, ati k'ile wa na le tubọ ni ilọsiwaju ati idagbasoke daradara si i, o ni, "e dide ki a fi ọpẹ fun Ọlọrun Olodumare?" Nwọn si kọ orin "Ọjọ na de, ti ENIA-DUDU wa di Ominira". Lẹhin eyi, Oloye Jọga-oke, Oluwo Ijọ Ilupesi ka ẹkọ lati inu Odu Ifa-Mimọ.

Lẹhin eyi ni nwọn tun kọ orin, Oloye Ogundare Awiṣẹ Apena Eko si wure, bẹ ẹ na si ni apapọ awọn ijọ ẹlẹsin Iṣẹṣe tun ṣe iwure lọkọọkan pẹlu.

Eto Isin na pari pẹlu iwure lati ẹnu Oloye Fagbemi Ajanaku, Araba Eko.

Awọn aṣoju ti nwọn ṣe iwure na ni Aṣoju awọn onIṣẹṣe Ilẹ Ibo, Ilẹ Hausa, apapọ awọn alahunni, olorisa-nla, ọlọṣun, onisango ati ọlọya, onigunnu, onigẹlẹdẹ ati Yemọja, elegungun ati elegungun-Ado, oloriṣa, alagẹmọ, oloro ati ẹlẹluku, ọlọsanyin, oloogun ati babalawo.

Aworan ẹgbẹ ọtun yi ni ti igbati Apapọ Ẹgbẹ Awọn Ẹlẹsin Iṣẹṣe Eko ati yika agbegbe rẹ nṣe Idupẹ fun ajọyọ Ominira Apapọ Ijọba Naijiria ninu Gbọngan Ile Isin wọn ni Isalẹgangan l'Eko ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi. Awọn ti o duro lati ikangun apa-osi ni Oloye Ogunlana Keji, Ọbanikoro Eko; Ọpa Ọba; Oloye Fagbemi Ajanaku Araba Eko; Oloye Fasanya Arijẹ, Araba Ikorodu; Oloye Dosunmu Oletubọ, Alaṣẹ Liwe Ikorodu, Oloye Adebayọ Adegbodu, Oluwo Ipẹru.






## Taji loju oorun Ki o si ṣ'ara giri!

Pẹlu ANDREWS LIVER SALT



O so le jẹ igbadun aiye nigbati ara ba nkun ọ. Agbẹdẹ nro ọ. ara ndun ọ o si kan ọ yipo ara. Ma a mu Andrews Liver Salt lojojumọ ki o si di alagbara ẹgbẹ ṣire! Idan Andrews Liver Salt ti o nho ṣuṣu yio jẹki o ni alafia gbogbo ọjọ. Da ara rẹ pọ mọ ẹgbẹrabẹrun awọn enia ti o ti ri i pe Andrews jẹki awọn lọwọ lati taji loju oorun ki nwọn si ṣ'ara giri.



ANDREWS YIO RAN Ọ LỌWỌ LATI Ş'ARA GIRI LẸKAN SI I LỌNA MẸTA

1. Andrews ọni hiho ṣuṣu yio ta ẹdọ rẹ ji-ile agbara ara rẹ
2. Yio fọ inu rẹ mọ jade yio jẹki ara rẹ ṣiṣẹ deede lati jẹki ẹjẹ ara rẹ yan dada.
3. Yio jẹki inu rẹ ni adun—yio mu oorun buruku ẹnu rẹ kuro.

AKIYESI
O le ri Andrews ra ni opọkuyọku, mimu lẹkan, awọn idi kekeke . . . tabi awọn apolo ti a ti mọ dada.



LARỌ, LỌSAN TABI LALẸ . . MU

ANDREWS LIVER SALT

FUN FIFỌ INU . . . . FUN OKUN ARA



## Rorẹ ati Awọ-ara ti ko dara yio san larin wakati mẹrinlelogun

NIXODERM Jẹ egbogi apoju pataki olorisi oogun meje ti o jẹ ipara funfun ti o nyara ba aleebu awọ-ara ja bi Ekuru, Rorẹ Ara-sisu, Lapalapa, Ogodo, Eela-Ọlọrọnto, Owo-inu Awọ-ori-ṣiṣi, Kokoro-jerun-jerun ati Isakaṣẹ NIXODERM nṣiṣẹ ni kiakia a si da ara-hihun duro larin iṣeju meje. O le ri agbayanu iyipada lẹhin ọjọ kini ti o ba lo o. Ṣa fi pa oju ibiti o ndun o ni awọ-ara ki o to lọ sun. Tiripẹpẹ ni yio dimọ ibẹ gẹgẹbi ibọwọ-aleeri a si ma a ṣiṣẹ nigbati iwọ ba nsun. Nigbati o ba dide ni ọjọ keji, wa a ri i pe awọ-ara rẹ ti mọ kedere, a di akotun, a jọlọ, a si ṣe mulọmulọ. Larin ọjọ die, ẹnu yio ya awọn ọrẹ rẹ si iyipada na.



SIWAJU LẸHIN

Maṣe jẹki idaamu mu ọ padanu awọn ọrẹ rẹ nipa pe o ni awọ-ara buruku. Lo NIXODERM loni ki o si ri bi gbajumọ rẹ yio ti tubọ ga si. NIXODERM ntete yara ṣiṣẹ nitoripe o mba awọn oniruru kokoro ti o nda awọ-ara laamu ja a si pa gbogbo wọn. Ra NIXODERM ni Ile Egbogi adugbo rẹ loni. O gbọdọ ni itẹlọrun pẹlu rẹ, bibẹkọ, a ti ṣeleri lati da owo rẹ pada.

NIXODERM


## Ẹ ma a ka iwe Irohin Yoruba nigba gbogbo

AWỌN mẹsan ninu olubaṣiṣẹpọ Ọgb Shamonda ni ifiwe-ranṣẹ (Post Of ẹka Ẹka Apọngbọn l' ẹyẹ idagbare fun un ilọ ti o nlọ si ilu C fun ilọsiwaju ẹkọ.

Nwọn ṣe adura f wọn na pe ki Ọlọr un ni nkan ti o nlọ ati pe ki o si pada ba awọn pẹlu inu did alafia.

Aworan oke yi ni ya fun iranti ọjọ Awọn ti nwọn joko ọwọ osi ni Ọgbẹni S sanya, Akinyẹle, Sh da, Silva ati On Awọn ti nwọn duro ọwọ osi ni Ọgbẹni Ak Aderounmu, Ogun Adeboye ati Oworu.

# Apapọ awọn ẹlẹsin Iṣẹṣe ṣe isin idupẹ ominira Naijiria





## Erin wo! Jinata Abikẹ filẹ ṣaṣọbora

OFFA-IBARE



LIJEBU-ODE


# Taji loju oorun Ki o si ṣ'ara giri!

Pẹlu ANDREWS LIVER SALT





ANDREWS

LIVER SALT



## Rorẹ ati Awọ-ara ti ko dara yio san larin wakati merinlelogun



NIXODERM



Ẹ ma a ka iwe Irohin Yoruba nigba gbogbo



# Jan LAKUREGBE! ni kumọ nla kan





ALGESAL



# Surf ni AGBARA IDAN

-lati jeki aṣọ mọ dada!




SURF ni irọrun ti o dara

ju lọ fun fifọ aṣọ mọ gara!




SIERA radio

NPE NAIJIRIA

SIERA radio

NPE NAIJIRIA




SIERA

NI AWỌN ẸRỌ-REDIO TI O DARA-
JULỌ NI NAIJIRIA
lọ wo awọn orişirişi agbayanu rẹ ti o wa
lọdọ awọn onibara rẹ LONI

JOHN HOLT

ni o npin in ti o si ntun ụn şe yika gbogbo NAIJIRIA

Awọn Onişowo Ile-Itaja:- UTC DEPARTMENT STORES, LAGOS ATI AWỌN GBAJUMỌ ONIŞOWO NLANLA YIKA GBOGBO NAIJIRIA



# Itumọ Ala awọn onibere

( Lati ọwọ Josẹfu Alala, Mushin )

RAPHAEL ADEBISI APELEGAN, Akurẹ—Ewu ti iba wu ọ ti rekọja, ṣọra nitori eyiti o tun mbọ.

BAYO, Ọwọ—Ala rere ni eleyi, ere pupo nibi iṣẹ ni

A. BABALOLA, Ibadan—Ala awọn ajẹ ni eleyi, ṣọra gidigidi.

L. A. KỌYA, Eruwa—Ijongbọn ti o ko fọwọ ara rẹ fa, yio wa ba ọ, ṣọra gidigidi laseko yi nipa ija jija.

KASUNMU Driver, Lagos—Ala rere ni, igbega ninu iṣẹ yio wa fun ọ laseko yi.

LIADI AMAO, Pramkese, Ghana—Igbega mbọ wa fun ọ laipẹ, ṣugbọn ṣọra gidigidi ki awọn ẹni ibi ma ba a ba ayọ na jẹ.

K. A. SHITTU, Imọta Ikorodu—Ala buburu ni eleyi, ẹnikan ti o gbọkanle ko ni pẹ wa tan ọ jẹ, ṣọra gidigidi k'o ma ba a bọ sinu takute rẹ.

SALAMI AGBEDẸ, Ọyọ—Ala buburu ni eleyi, ṣọra ki o ma ba a bọ si takute awọn iya.

JIMỌH IBA, AKABA, Kumasi Ghana—Ala buburu ni itumọ rẹ, ijongbọn ti o ko f'ọwọ fa yio kọ lu ọ, ṣọra gidigidi.

K. AYINLA, Onigbongbo—Ala rere ni, ṣugbọn ikilọ ni o tun jẹ fun ọ nipa gbigba nkan jẹ lọwọ enia.

JAMEṢ ỌDẸYẸMI, Ibara, Abẹokuta—Ti o ba ri omi loju ala ti o ba ri rukuruku, ṣọra ki o ma ba a bọ sinu idẹkun ọmọ araiye, ti o b asi jẹ ọdọ ti o mọ gaara ni, ohun rere ko ni pẹ yọ si ọ lọwọ.

JOSIAH IBIDAPỌ, Ile-Ifẹ—Itumọ ala na ni ibanujẹ nipa iku ojiji, ṣugbọn ṣọra gidigidi lasiko yi ki o ma ba a lugbadi ogun lakaiye.

ỌLABANJI ADEDAMỌLA, Abẹokuta—Igbega ati okiki ni ile aiye ni itumọ ala yi, ṣugbọn ṣọra nipa awọn agboyi s'ọyi ọrẹ, ki nwọn ma ba a fa abibu wa ba ọ.

SEGILỌLA AROYEWU, Offa.—Rere ni itumọ ala na, ohun rere ti o nfẹ ko to ọ lọwọ, ko ni pẹ ki o to bọ si o ti o ba ni ifarada ati suru.

ỌLARONKẸ LAYỌNU, Gbọgan—Ala buburu ni eyi, ṣọra ki o ma ba a bọ si ọfin ọmọ araiye.

EZEKIEL ADEDOKUN, Ibadan—Igbega ninu ẹgbẹ ati ogba ni itumọ ala yi.

ISRAEL AREO, Gombe—Ala rere ni, iwọ yio bori iṣoro gbogbo ti o wa niwaju rẹ, ṣugbọn ṣọra lọdọ awọn ọrẹ korikosun ki nwọn ma ba a tun sọ ọ di ẹni ẹhin.

MURANỌ ASUNMỌ, QI, Kano—Iwọ ko ni pẹ gbọ iro rere lati ọna jinjinrere wa, ṣugbọn ṣọra nipa fifi inu han ọrẹ.

MORẸNIKẸ, Ọyọ—Idamu yio wa fun ọ lasiko yi, ṣugbọn ti o ba ni suru iwọ yio leke iṣoro na.

M. A. ADE, Abẹokuta—Ala rere ni, iwọ ko ni mọ iṣẹ ni asiko yi, iwọ yio ni alafia ati ẹmi gigun.

KARIMU YOUNG BOY, Okeiho—Ṣọra gidigidi ki o ma ba a bọ si idẹkun awọn ọmọ araiye.

PIUS OLOWE, Ikare—O le pẹ, o le ya, iyawo na yio fẹ ọ.

SAMUEL DADA, Lagos—Ala rere ni eleyi, ohun ti o ba dawọle ni aseko yi rere ni yio ma a jasi, ṣọra lọdọ ọrẹ ki nwọn ma ba a ko ba ọ.

Bere itumọ ala rẹ lọwọ Josẹfu Alala Elephant House, 214, Broad Street, Lagos.

## Ijẹbu-Ijẹsha

Lati oju ewe kẹrin

Iru iwa afipa-tẹniloriba bayi ni nwọn nhu si awọn Ọba ẹlẹgbẹ wa lati Ekiti. Eyi ni o mu ki nwọn pada si ilu wọn lai ba wa ṣe pọ mọ titi ti o fi di oni yi. Ogagun Major W. R. Reeve Tucker ni o wa ni Ijọba Gẹẹsi ni Ilesha ni ọdun 1901 de 1902

Ọwa Ilesha ni Owa-Ilesha njẹ nigbana, ṣugbọn nigbati a gba Ominira Igbimọ Ẹkun Ijẹsha (Divisional Council).

## Awọn ọmọ ilu Ọyan ṣe ipade

(Lati oju ewe karun)

Nwọn ni bi awọn ko tilẹ ni aṣoju ninu Ile Igbimọ Aṣofin mejeji ti o wa ni Ipinlẹ na, njẹ ko ha yẹ ki Ijọba ṣe ẹtọ nipa ọrọ oye Ọlọyan na?

Awọn ti nwọn sọrọ nibi ipade na fi tẹdun-tẹdun sọrọ, nwọn si gba adura fun anfani ilu wọn. Awọn alakoso ipade na ni Ọgbẹni James Ọlaniran, alaga; Sanusi Olowoye, akapo; Oyeniyi Ajayi, akọwe ati Asunwọ Adeyẹmi.


**Ko si Ẹsanra ati irora mọ!**

**Mu alafia rẹ lojojumọ**

Bi ere ni yio ri nigbati o ba bẹrẹ mu TISANE de DURBON! Gbogbo iyọnu rẹ yio folo, igbesi-aiye a tun di akọtun dada. Wa a si bẹrẹ jẹ igbadun aiye laipe. Mu TISANE de DURBON —

**Ki o si fi opin si**

- ★ AIRIGBEYA
- ★ IYỌNU ẸDỌ ATI ERE
- ★ INU-RIRUN
- ★ INU-ṢIṢU
- ★ ARAWỌN-ARA PATI-PATI
- ★ IRORA LAKUREGBE
- ★ IRẸWẸSI

TISANE de DURBON ntun ele fẹ ṣe. Eyi ni o jẹki ara rẹ ya-gaga, ki o si kun fun agbara. TISANE de DURBON jẹ apejuwe nkan iyanu ti nwọn fi eweko-tutu ṣe. O jẹ nkan mimu ti ẹda ti o dara ni ilopo ona ọgọrun fun ọ!

FUN ILERA TITUN ATI OKUN-INU



Bi o ba fẹ ri alafia lojojumọ ki o si ri igbẹ ya deede; ma a mu TISANE de DURBON.

**TISANE de DURBON**

Ma a fi oju wa a ninu apoti pupa didan!

Agbayanu Egbogi Atẹjẹṣe

D.P.I. LTD. 1, AERODROME ROAD, P.M. BAG 1006 APAPA






**AMAMA nfun ni ni agbara**

Manufactured by Glaxo Laboratories (Nigeria) Ltd., Apapa.
Trade enquiries: Glaxo-Allenburys (Nigeria) Ltd., Lagos, Aba and Kano

# Alapara pade Alawiye

## "Kini iṣẹ Gomina-Agba titun ninu ominira Apapọ Ijọba Naijiria?"

ALAPARA—Ẹ ku arọ o, Ọgbẹni Olotu.

OLOTU—Ṣe alafia ni ẹ wa, ṣe alafia ni gbogbo ile wa, ṣe ẹṣin njoko o?

ALAPARA—Ẹ tun de o, Olotu, mo gbọ gbogbo kiki ti ẹ ki mi, ṣugbọn ede ti ẹ fọ kẹhin fi ki mi yi ni ko ye mi si dada, nko gbọ Yoruba de bẹ.

OLOTU—Ede wo ni o?

ALAPARA—Lẹhin ti ẹ ti bere ile, bere ọna lọwọ mi tan, ẹ si bere pe "Ṣe ẹṣin njoko o," Iyẹn ni ko ye mi si nigba ti nko kuku ni ẹṣin ni eekan. Ẹ jọwọ ẹ la a ye mi, kini itumo "Ẹṣin njoko?"

OLOTU—Iditi ọrọ rẹ fi nsu mi ni yi, nitori, ki o ti mọ oran tan, ki o tun ma a bere, o fẹran ki o ma a fi ọrọ wa mi lẹnu wo.

ALAPARA—Ti amoran tun bere ọran kọ ni temi, ohun ti mo fẹ ki ẹ mọ daju ni pe, pataki ohun ti o ngmu mi ma a wa fi ọrọ jomitoro ọrọ lọdọ nyin ni lati ma a gbọ Yoruba -ijinlẹ nitori ọpọlọpọ awọn owe iwoyi ni ede Gẹẹsi ko jẹki nwọn mọ ede Yoruba sọ taara mọ, ṣugbọn ti mba de ọdọ nyin, a ma a mu mi ranti baba mi ologbe, bi on ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ ti i ma a sọ Yoruba ti ko ni abula ninu.

OLOTU—Iru Yoruba wo ni nwọn npe ni abula.

ALAPARA—E ṣeun, ṣeun, ṣeun iru Yoruba abula na pe orisi-meji, ikan a npe e ni anogo, a si tun npe ekeji ni tẹgba-toyinbo ni iha riwa ni Abeokuta lọhun.

Ekini ni ti awọn ti ko gbọ ede Oyinbo lati ma a fi ṣe abula Yoruba, ṣugbọn ti o ba jẹ pe, awọn agba Yoruba ba soro ti nwọn si nfi owe kookan so o po, larin ki i ye won. Ekeji ni ti awa oloyinbo ti a ba nsọrọ pẹlu awọn ẹlẹgbẹ wa ni "John njẹ o wa si ibi Function yẹn lana?" Yes, mo wa, ṣugbọn mo late diẹ ni, ṣe wa a try ri mi ni irọlẹ ọla? Perhaps, ṣugbọn mo ro pe ma a busy diẹ, lori kini o fẹ busy le? mo ti ni appointment kan tẹlẹ, tani fun ẹ ni appointment? Brother mi ni o sọ pe, meeting kan yio wa ni ile uncle wa l'Ebute-Mẹtta ni 4.30. Kini ẹ fẹ discuss nibẹ?

Is a family matter ati pe agreement kan wa ti awọn agba wa fẹ sign si, ti gbogbo wa ba agree. All right o le call at my place at any time. Mo gbọ o I'll see you later on. Ati bẹẹ bẹẹ lọ. Ṣe ọrọ mi ye nyin wayi?

OLOTU—Ọrọ rẹ ye mi yekeyeke. Ti a ba ki enia, ti a ba bi i lere pe, ẹṣin ko njẹ oko bi o? Iyẹn ni wipe, ẹni ti a nki ki iṣe apọn (ẹniti ko ni aya ni ile) ati wipe on pẹlu iyawo rẹ ngbadun ara wọn bi tọkọ-taya laisi ede-aiyede kan larin ara wọn, iyẹn ni pe, iyawo nse ọbẹ adidun fun un ni aseko ti o yẹ, ọkọ paapa si npe iyawo rẹ ni orun laseko. Ṣe o ye ọ wayi?

ALAPARA—Ki Oluwa ma jẹki agba tan ni orilẹ. Ọrọ nyin ye mi, o mu inu mi dun, o si mu ara mi ya gaga, nitorina mo da nyin lohun pẹlu igberaga pe "ẹṣin njoko o."

OLOTU—Ọran tan!

ALAPARA—Ẹ ṣe, mo dupẹ, ọpọlọpọ ni o ya ope bi iru temi ti alaye nyin yio si ṣe ni anfani nigbati nwọn ba ka a.

OLOTU—Duro na Alapara, kiniṣe ti nko fi ri ẹ ni ọjọ Abamẹta ti o kọja.

ALAPARA—Bẹni ọrọ ni i ba mo ko-moro wa, ati pe, ẹniti o bere ọrọ ni i fẹ idi rẹ gbọ, ngo si sọ ọ fun nyin.

### AZIKIWE DI GOMINA AGBA

Bi mo ti pe ki ngma a bọ wa si ọdọ nyin ni mo tajukan, ni mo ri ọrẹ mi kan t la npe oruko inagijẹ rẹ ni Alawiye, "Aso'rogbo-sẹnu b'ọkunrin sọrọ, asọ-alawẹ obi sẹnu b'obirin,

(Wo oju ewe kejila)

Nje o ti ri AJAPA ALAWỌ-ALIGA RI BI?



### O ṣẹṣẹ de si ile-itaja adugbo rẹ ni!

Ajapa Alawọ-Aliga ni ẹni ayanfẹ ti o le ri lara gbogbo awọn Panu-onjẹ ti Ile-Iṣẹ Alumaco titun ṣe ni Apapa. On ni o joko lori awọn ikoko-irin-yanranyanran ti o si nwoye yi. O le jẹwipe bi o ti wi ni ni o darajulọ ti o le ra—wọn le faya tabi ki nwọn dipẹta. afuyẹ ati awọn panu ti o ndan pẹlu ifalyabalẹ si ara rẹ nibẹ o ri—awọn ikoko ati panu rẹ lagbara to bẹ ẹ gẹ ẹ, nwọn ko Nwọn tun dinwo pẹlu nitoripe nwọn ni alopẹ pupọ ju iru awọn awo-onjẹ miran lọ. Ma a fi oju wa Ajapa Alawọ-Aliga ni Ile-Itaja adugbo rẹ.

AWỌN AJAPA ALAWỌ-ALIGA jẹ ayanfẹ pataki ninu gbogbo awọn Ile-idana igba isisiyi.

ẸNYIN ONIṢOWO
Bi ẹ ko ba ti i ra awọn Ajapa Alawọ -Aliga sinu ṣọbu nyin—ẹ tete wa ri wa kiakia.

Awọn ti o nṣe nikan ni

ALUMACO, P.O. Box 60, Apapa, Lagos,
Telephone: — 55715

## FUN EREE (KIDNEY) RẸ NI OKUN

MA A GBADUN BI ỌMỌDE—KI O SI DABI ỌMỌDE

Ko si ohun ti o nsọ ọkunrin tabi obirin di arugbo ju aisan ati irora ti aiṣiṣe deede Eree (Kidney) ngmu wa lọ. Eyi ni o ngmu o ṣe aisan Itọ rukuruku, Didaji loru, ki itọ ma a jo o nidi, ki iho ile-itọ ma a hun ọ, Oyi Lakuregbe, Ẹhin didun, Ojugun riro ni Ibaaba loju, Orunkan wiwu, ki agbara dinku ati bẹẹbẹẹ lọ. CYSTEX yio ran ọ lọwọ lati sọ ẹlẹ re di akọtun kuro ninu omi-aisan ati oro ti o nwọ si inu gbogbo awọn iṣẹpo ati iṣan ara rẹ. Larin wakati mẹrinlelogun ni CYSTEX yio fi pa gbogbo kokoro-aisan ti o wa ninu Eree (Kidney), yio fun awọn Eree (Kdneys) lagbara a si le gbogbo omi-aisan ati oro lade. Ra CYSTEX lọwọ apoogun ti o ba ri, lori adehun pe yio mu ọ lara da tabi ki o gba owo rẹ pada. Ta saṣa nisisiyi! Larin wakati mẹrinlelogun ara rẹ yo ya, yio si wo o san patapata larin ose kan.

**Cystex** fun awọn Eree (Kidneys) Lakuregbe, Ile-Itọ.

## Fi Warakaṣi Kraft pese onjẹ daradara kiakia

O dara lori buredi tabi akara-oyinbo




Warakaṣi [illegible] uyu enia to bẹe gẹe. O ya lati fi pese onjẹ kiakia pẹlu irorun fun gbogbo ebi Enikẹni fẹran rẹ. Fi si ori buredi tabi akara-oyinbo fun awọn ọmọde nigbakigba ti ebi ba npa wọn. Bere fun Warakaṣi Kraft ni Ile-itaja. Wa a ri i pẹlu irorun ninu agolo onibulu ati yelo.

**KRAFT** FOODS LIMITED
Regina House, Marylebone Road, London N. W. 1.

IROHIN YORUBA

# Balewa ni Ijọba kan ko le tu Ijọba miran ka

(Lati oju ewe kẹta)

Lati Ibadan Ọlọla Abubakar ṣe abẹwo ilu miran ni Ipinlẹ Iwọ-Orun bi Ibinni, Ifẹ, Ilesha, Ọyọ ati Ogbomoshọ, Oloye Akintọla ki Ọlọla Abubakar ni oruko awọn Ọba, Ijoye ati ara ilu ẹkun Ọshun, eyiti on Oloye Akintọla jẹ ọkan ninu wọn. O ni inu gbogbo ilu dun lati gba a ni alejo, o ni on si ro pe Ọlọla Abubakar yio ti ri I fun rarẹ pe inu awọn ara ati Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun mọ si gbogbo ẹnikẹni. Oloye Akintọla sọ pe on fẹ ki Ọlọla Abubakar fi aye awọn Ijọba Ipinlẹ Naijiria si Ijọba Apapọ Naijiria han, ki ọkan gbogbo ẹnikẹni le fuyẹ.

Ọlọla Abubakar dupẹ lọwọ Oloye Akintọla ati awọn Ọba, Ijoye ati ara ilu Ọshun fun ẹyẹ ti nwọn ṣe fun on. Nipa aye ti awọn Ijọba Naijiria wa si ara wọn, Ọlọla Abubakar sọ gbangba pe Ijọba kan ko ni agbara lati pa Ijọba miran rẹ ni Naijiria. O ni olukuluku Ijọba Ipinlẹ Naijiria ni o ni ominira fun ra rẹ, ni o si le ṣe nkan t lo ba fẹ ni rere fun ilu rẹ lalai jẹ pe Ijọba miran le ṣe iranlọwọ na fun un, bi Ijọba ti o nfẹ iranlọwọ ba ke si Ijọba miran fun iranlọwọ.

Ọlọla Abubakar ni on ti gbọ, on si ti ri I ka pe Ijọba kan le tu Ijọba miran ka ni Naijiria. O ni eyi ko ri bẹ ẹ.



DA

INU-RIRUN DURO

Nigbati o ba ni irora ninu ikun rẹ, ohun ti o nfa idi rẹ nigbagbogbo ni pe omiro ti pọju nibẹ. Omiro yi ni o nfa arun-inu, inu-kikan-ni ati airi-igbẹ-ya.

Ṣa ti mu ẹgbogi Phillip's 'Milk of Magnesia' diẹ ........ yio si ko rirogun omiro na kuro, a si le irora na lọ werewere. Yio fun okun-inu lagbara lati ti gbogbo nkan ti o nfa irora na jade kuro lara.

Ko lewu, o rọrun lati lo, o si tu ni lara.

'MILK OF MAGNESIA'

Awọn ti o nṣe e ni

PHILLIPS

ODARA FUN GBOGBO ẸBI



# Alapara pade Alawiye

(Lati oju ewe kẹwa)

sọrọ, abu-iyọ si ẹrẹkẹ ṣe kampeni.

OLOTU—Ewo ni ẹ npe ni "Kampeni"?

ALAPARA— Olotu, ẹ tun de o, mo ti sọ pe amulumala Yoruba ni awa nsọ, "Kampeni ni ki a ma a polowo ẹgbẹ oṣelu fun awọn ara ilu fun idibo.

OLOTU—Unhun, o ye mi wayi, ma sọrọ rẹ lọ.

ALAPARA—Bi a ti nsọrọ ni o sọ fun mi pe ni ọjọ marun oni ni awọn yio ti Dọkita Nnamdi Azikiwe, Olori Igbimọ Awọn Agba-Oṣelu jẹ Gomina-Agba Apapọ Ijọba Naijiria Ọjọ na si ku ọla nisisiyi. Mo wa se ẹnu-foro bere lọwọ rẹ pe, kini iṣẹ Gomina-Agba titun jẹ ninu Ominira Apapọ Ijọba Naijiria?

ALAWIYE—O ṣeun, iwọ ko mọ pe ipo ti Ọlọla James Rebertson ti wa ri ni nwọn yio gbe Azikiwe si?

ALAPARA—Ṣebi Gomina-Agba ti wa fun Aṣoju Ijọba Gẹẹsi ri, nigbati a koi ti gba ominira? Ṣugbọn nisisiyi, a ti gba ominira, ẹniti yio ba si ṣe aṣoju Ijọba Gẹẹsi yio wa lọtọ gẹgẹbi awọn aṣoju ilu wa ti wa lọtọ ni ilu Lọndọnu ni ati pe, awọn ko si fi Oyinbo ṣe aṣoju wa ni ọhun, kini Azikiwe ti o jẹ ọkan pataki ninu awọn aṣiwaju oṣelu wa yio ti ṣe jẹ aṣoju Ijọba Gẹẹsi ni arin wa?

ALAWIYE—Emi paapa ti ro o wo pe, kini aye Gomina-Agba yio ti jẹ ni arin wa nigbati a ni Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria?

ALAPARA—Ibiti mo mbọ ni o ṣeṣẹ sọrọ de yi, a gbọ ti igba ti a ko i ti gba ominira pe, Gominia-Agba ni Olori, njẹ nisisiyi ti a ti gba Ominira, ti Ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa nṣe Alakoso Apapọ Ijọba na, tani wa ni ọga ninu on pẹlu Azikiwe ti yio jẹ Gomina-Agba? Mo si tun fẹ bi ọ lere pe, ti ẹ ba tun fẹ ṣe Kampeni nigba miran iru ipo wo ni ẹ o se apejuwe pe Balewa wa si Azikiwe?

ALAWIYE—Azikiwe ko si ninu ẹgbẹ oṣelu kankan mọ, ki o ma a wo wọn niran bi nwọn ba ti nṣe e si ni.

ALAPARA—Iyẹn ni pe, oye Gomina-Agba ti Azikiwe yio jẹ, ki o kan lọ simi, ki o ma a woran, bi nwọn ba ti nṣe ọran iṣelu si ni, tabi bawo?

ALAWIYE—O gbọ mi na. Alapara, ibere rẹ yi pọ ju temi lọ, ohun ti mo rọ pe wa a ṣe ni pe ki o lọ bere lọwọ akọwe Azikiwe paapa, bi o ba si wa pẹlu wa ninu ki a bọ ajaga Ijọba Gẹẹsi kuro lọrun patapata ni, tabi aṣoju Ijọba Gẹẹsi ni o nṣe ni, tabi o wa ni aye na fun isimi kuro ninu laala rẹ ni?

ALAPARA—Nibiti emi pẹlu Alawiye ba ọrọ na de niyi ti mo fi kuro ni ọdọ rẹ, tabi ẹ ni alaye diẹ ti ẹ o ṣe nipa rẹ?

OLOTU—Ṣi lọ simi le ori ọrọ ti Alawiye sọ fun ọ yi na, ki o si ma a woye.

ALAPARA—O darọ o, o digba-oṣe o.

OLOTU—Ku abọ o, ipade wa bi oyin o.






Published by Allied newspapers Limited, Elephant House 214, Broad Street, Lagos and printed for them by Amalgamated Press of Nigeria Limited. Fun owo "IROHIN YORUBA" ọdunkan—Eko ṣile mejọ ati kobo mejọ (8/8d.). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun sile metala (13s.) Olotu S. M. Ademuyiwa, 2 Idumagbo Street, Odi-Olowo, Mushin.